**Research Note**

# Lílo 'BBC News Yorùbá' fún Ẹ̀kọ́ Yorùbá ní Amẹ́ríkà

Victor Temitope Alabi
Center for Language Studies
Department of World Languages and Cultures
Brown University
victor_alabi@brown.edu

## Abstract

I examined various means by which interviews made on 'BBC News Yorùbá' could be employed in Yorùbá language pedagogy in America. I then explored different topics that are generally treated in these interviews on 'BBC News Yorùbá' like politics, religion, sports, and business, and I classified these interviews into two: interviews made with an individual and interviews made with several people. Furthermore, I proposed a framework, which I named Yorùbá Dialectal Model (YDM). The framework submits that creators of authentic language resources in Yorùbá such as interviews (as I argued in this paper) and films (see Alabi, 2017) should consider the strict or the near strict use of the Yorùbá language in the communicative skills of writing and speaking. In a situation where new words that do not exist in Standard Yorùbá have to be borrowed; such words should be borrowed from dialects of Yorùbá rather than other languages. Finally, I analyzed an interview with Chief Ọbásanjọ́ to show the import of the framework and of interviews as authentic pedagogical resources in the Yorùbá language classroom across America.

## Àṣamọ̀[1]

1 Mo kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ yìí ní ibi ìpàdé American Association of Teachers of Yorùbá (AATY) nínú ìpàgọ́ African Language Teachers Association (ALTA) ní ọdún 2021. Mo dúpẹ́ gidi lọ́wọ́ àwọn èsì àti ìmọ̀ràn tí mo rí gbà ní ibi ọ̀rọ̀ náà.

Mo wo àwọn ọ̀nà tí a lè fi lo ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò lóri 'BBC News Yorùbá' láti kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní Amẹ́ríkà. Mo tún wo oríṣìí àkòrí tí wọ́n má ń bi àwọn tí wọ́n ń ṣe ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú, bíi ọ̀rọ̀ òṣèlú, ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn, ọ̀rọ̀ ìdárayá àti, ọ̀rọ̀ nípa òwò ṣíṣe, mo sì sọ̀rọ̀ nípa oríṣìí ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò méjì: ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú èèyàn kan, àti ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ọ̀pọ̀ èèyàn. Ní àfikún, mo gbé ìlànà tuntun kan kalẹ̀, tí mo pè ní Yorùbá Dialectal Model (YDM). Ìlànà náà ṣàlàyé pé àwọn aláṣẹ tí wọ́n ń ṣe oun èlò tí a lè lò láti kọ́ ẹ̀kọ́ nínú kílàsì bíi ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò (tí mo sọ̀rọ̀ nípa nínú ìwé yìí) àti fíìmù (ẹ wo Alabi, 2017), kí wọ́n wo ìlò èdè Yorùbá dáadáa nínú iṣẹ́ wọn nínú ọ̀rọ̀ sísọ àti ọ̀rọ̀ kíkọ. Ní àwọn ìgbà tó bá pọn dandan láti lo ọ̀rọ̀ àyálò tí kò sí ní èdè Yorùbá àjùmọ̀lò, kí wọ́n yá àwọn ọ̀rọ̀ náà láti àwọn ẹ̀ka èdè Yorùbá dípò látàrí àwọn ọ̀rọ̀ nínú èdè míràn láti àwọn ìlú àbí Orílẹ̀-èdè míràn. Níparíparí, mo ṣe àtúnpalẹ̀ ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Olóyè Ọbásanjọ́ láti ṣe àlàyé bí a ṣe lè lo ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò gẹ́gẹ́ bíi oun èlò pàtàkì láti kọ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní Amẹ́ríkà.

## Ìfáàrà

Òpó 'BBC News Yorùbá' ṣíde iṣẹ́ ní ó lé ní ọdún márùnún sẹ́yìn. Oríṣìí ìròyìn ni ó wà ní orí 'BBC News Yorùbá'. Bákan náà, oríṣìí ìròyìn tó wà nípa èdè àti àṣà Yorùbá ni a lè rí ní orí 'BBC News Yorùbá'. Oríṣìí ètò ni a tún lè rí ní orí 'BBC News Yorùbá', tó jẹ́ ìròyìn tó sì jẹ́ oun àǹfààní fún kíkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá ní Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà. Oríṣìí ìròyìn abẹ́lé àti ti òkè òkun tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè gbọ́, tí wọ́n sì lè kà ni a lè rí ní orí 'BBC News Yorùbá'. Àpẹẹrẹ ni ìròyìn nípa ìṣe òṣèlú, eré ìdárayá, ẹ̀sìn, ojú ọjọ́, òwò ṣíṣe, ayẹyẹ, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ní àfikún, oríṣìí fídíò àti àwòrán ni ó wà fún ẹ̀kọ́ èdè àti àṣà Yorùbá. Oríṣìí fídíò nípa èdè àti ẹ̀dá èdè Yorùbá náà tún wà fún ẹ̀kọ́ Yorùbá, fún àpẹẹrẹ, ẹ wo ẹ̀kọ́ nípa ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ láti ọwọ́ Olùkọ́ Kẹ́mi Abíọ́dún[2]. Àpẹẹrẹ àwọn àwòrán ní orí òpó 'BBC News Yorùbá' ni bíi pípарí òwe. Èyí túmọ̀ sí pé 'BBC News Yorùbá' wúlò ju kí a kàn ri gẹ́gẹ́ bíi ọ̀nà láti lè gbọ́ ìròyìn. Ìwúlò míràn ni lílo àwọn ìròyìn yìí fún gbígbọ́ àti kíkà Yorùbá ní kílàsì. Oríṣìí nǹkan ni wọ́n gbé kalẹ̀ fún àǹfààní ẹ̀kọ́ Yorùbá tó jẹ́ oun àǹfààní fún ẹ̀kọ́ kíkọ́ ní àwọn ilé-ìwé wa. Nínú ìwádìí mi yìí, mo lo àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò láti sọ̀rọ̀ nípa ìwúlò 'BBC News Yorùbá' nínú ẹ̀kọ́ kíkọ́. Àǹfààní pàtàkì kan tó wà nínú àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò ni pé púpọ̀ nínú àwọn èèyàn tó ń sọ̀rọ̀ ní orí 'BBC News Yorùbá' ń sọ̀rọ̀ bí wọ́n ṣe má ń sọ̀rọ̀ ní ojú ayé. Èyí yàtọ̀ sí nǹkan tí a rí ní orí fíìmù. Ní orí fíìmù (ẹ wo Alabi, 2022), ọ̀rọ̀ àwọn òṣèré jẹ́ oun tí akọ̀tàn àti olùdarí eré bá fẹ́ kí wọ́n sọ. Nítorí náà, èyí fi hàn ìwúlò àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò ní orí 'BBC News Yorùbá'. Ó sì ṣe pàtàkì láti sọ pé a lè lo àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí fún àwọn ọlọ́dún ìkíní, ọlọ́dún ìkejì, ọlọ́dún ìkẹ́ta, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ó dá lóri iṣẹ́ tí olùkọ́ bá fún wọn.

2 https://www.bbc.com/yoruba/56493548

## Ìròyìn

Ìròyìn jẹ́ oun tuntun tó lárinrin tí a má ń gbọ́ pàápàá lóri ẹ̀rọ àbí tí a má ń kà. Ó sì ṣe pàtàkì pé a má ń sọ ìròyìn náà fún àwọn èèyàn, a sì má ń kọ àbí tẹ ìròyìn, fún àpẹẹrẹ, sí ọ̀rẹ́ wa lóri ẹ̀rọ́ ìbánisọ̀rọ̀. Oun mẹ́rẹ̀rin yìí (gbígbọ́, kíkà, sísọ, àti kíkọ) ṣe pàtàkì nínú kílàsì Yorùbá. Oun tó jẹ́ ìròyìn sí ẹnì kan lè má jẹ́ ìròyìn sí ẹnì kejì. A má ń gba ìròyìn ní oríṣìí ọ̀nà, fún àpẹẹrẹ, ní orí ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì, ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán, àbí nínú ìwé ìròyìn. Oríṣìí ìwé ìròyìn ni a ní ní ilẹ̀ Yorùbá bíi *Aláròyé* àti *Yorùbá News*. Àwọn ìwádìí wà lóri wọn (ẹ wo iṣẹ́ Akinseloyin, 2020; Akangbe, 2020; Bolarinwa, 2020; Ibikunle, 2020; àti Olunlade, 2020). Yàtọ̀ sí ìwádìí lóri àwọn ìwé ìròyìn yìí bíi *Aláròyé*, Salawu (2004a), (2004b), àti (2004c) tún ṣe ìwádìí nípa oríṣìí àwọn ìwé ìròyìn ní ilẹ̀ Yorùbá àti ìhà tí àwọn èèyàn pàápàá àwọn alákọ̀wé òde òní kọ sí wọn. Bákan náà, Schleicher (1997) ṣe iṣẹ́ nípa kíkọ ìròyìn láti orí ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì sílẹ̀ fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá. Ọ̀ṣunnúgà (2013) wo oríṣìí kókó inú ìwé ìròyìn.

Ìròyìn lóri ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì àti ìròyìn lóri ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán tí wọ́n ní àǹfàní gbígbọ́, ti wà fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún. Àwọn ìwé inú ìròyìn ti wà bákan náà, kódà, a lè gbọ́ àwọn kókó inú ìwé ìròyìn lóri ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì àti amóhùnmáwòrán Ní òde òní a tún ti ní àfikún sí ìròyìn ti orí ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì àti amóhùnmáwòrán. Àfikún yìí ni a rí lóri ẹ̀rọ ayárabíàṣá nípasẹ̀ ẹ̀rọ ayélujára. Nísisìyí a lè rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwé ìròyìn Yorùbá lóri ayélujára bíi *Olóṣèlú*[3], *Aláròyé*[4], àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Kódà *Olóṣèlú* wà lóri òpó X (Twitter). Òpó ìròyìn míràn tó yàtọ̀ sí oun tí a ti mọ̀ bíi ti orí ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì, ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán àbí ìwé ìròyìn ni 'BBC News Yorùbá'. Ó yàtọ̀ nítorí ìsọ̀rí BBC News ti àgbáyé ni ó jẹ́, àti pé ó kó iṣẹ́ ẹ̀rọ asọ̀rọ̀mágbèsì, ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán, àti ìwé ìròyìn papọ̀. A lè gbọ́ ìròyìn, a sì lè ka ìròyìn púpọ̀ lóri 'BBC News Yorùbá'. A lè rí ìròyìn 'BBC News Yorùbá' lóri ayélujára[5]. Òótọ́ ni pé 'BBC News Yorùbá' wà lóri òpó Facebook, X (Twitter), àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Mo lo fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò lóri 'BBC News Yorùbá' láti ṣe ìtúpalẹ̀ àǹfàní rẹ̀ fún ẹ̀kọ́ Yorùbá ní Amẹ́ríkà.

## Ìsọ̀rí oríṣìí fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò

Mo pín oríṣìí àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò lóri 'BBC News Yorùbá' sí méjì nípasẹ̀ àwọn tí wọ́n fi ọ̀rọ̀ wá lẹ́nu wò. Àkọ́kọ́ ni fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ọ̀pọ̀ èèyàn, fún àpẹẹrẹ, fídíò nípa ìṣòro tí ìlú kan ń là kọjá (ẹ wo àpẹẹrẹ àìsí omi mímu ní abúlé Ẹlẹ́ga[6]). Àǹfàní pàtàkì nípa àwọn irú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí ni pé àwa olùgbọ́ máa mọ nǹkan tó ń ṣẹlẹ̀ látàrí ìrírí àti ìhà oríṣìí èèyàn tí ọ̀rọ̀ náà kàn. Ìkejì ni fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú èèyàn kan, fún àpẹẹrẹ, èèyàn tó

3 https://oloselu.ng/
4 https://alaroye.org/
5 https://www.bbc.com/yoruba
6 https://www.bbc.com/yoruba/56480831

jẹ́ gbajúmọ̀ (ẹ wo fídíò ọ̀rọ̀ pẹ̀lú òṣèré Ọmọ́tọ́lá Jọláadé Ekéìndé[7]). Èyí máa jẹ́ kí olùgbọ́ mọ nǹkan púpọ̀ nípa èèyàn àbí oun kan pàtó nípasẹ̀ nǹkan tí ẹni tí à ń fi ọ̀rọ̀ wá lẹ́nu wò náà bá ń sọ.

Àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú èèyàn kan àbí pẹ̀lú ọ̀pọ̀ èèyàn lárinrin nítorí kò sí ẹni tó ń bèèrè ọ̀rọ̀ kànkan fún ìdáhùn. Yálà àwọn ìbéèrè ń jẹ yọ ní orí fídíò náà, àti pé (àwọn) ẹni tó ń sọ̀rọ̀ ń sọ ọ̀rọ̀ nípa nǹkan kan ní pàtó. Oun tó tún dára pẹ̀lú irú àwọn ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí ni pé nígbà míràn, a má ń rí àwọn iṣẹ́ àbí àyíká (àwọn) ẹni náà, bí wọ́n ṣe ń sọ̀rọ̀. Ó ṣe pàtàkì láti sọ pé kódà tí (àwọn) ẹni tó ń sọ̀rọ̀ bá ń sọ èdè míràn bíi èdè Gẹ̀ẹ́sì, a máa rí ìtúmọ̀ ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì náà kà ní èdè Yorùbá. Èyí ṣe pàtàkì nítorípé ó dára kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ gbìyànjú láti máa sọ̀rọ̀ tààrà ní èdè Yorùbá láìsí àmúlùmálà pẹ̀lú èdè míràn (ẹ wo Alabi, 2017). Èyí fi ara mọ́ ìlànà tuntun (Yorùbá Dialectal Model) tí mo gbé kalẹ̀. Tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ bá ń wo fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò, fún àpẹẹrẹ, tí wọ́n wá ń gbọ́ ọ̀rọ̀ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì láàárin èdè Yorùbá, ó dára kí a rí ìtúmọ̀ ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì náà kà ní èdè Yorùbá, ní orí fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà. Ní orí fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ nínú ìwé yìí àti àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò ìmíràn (fún àpẹẹrẹ, ẹ wo ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Ọba Francis Olúṣọlá-Àlàó[8]), a ò rí ọ̀rọ̀ Yorùbá kà rárá lóri àwọn fídíò náà, bẹ́ẹ̀, ọ̀rọ̀ sísọ jẹ yọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì. Ó dára láti sọ pé òótọ́ ni pé a lè rí ọ̀rọ̀ kà ní èdè Yorùbá ní àwọn ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò ìmíràn tí a là kalẹ̀ ní àwọn gbólóhùn ọ̀rọ̀ tó kàn ní ìsàlẹ̀. Fún ìwádìí yìí, mo wo àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí wọ́n ṣe pẹ̀lú èèyàn kan.

Oríṣìí àwọn ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú èèyàn kan ni ó wà lóri ‘BBC News Yorùbá’. Mo là wọ́n kalẹ̀ sí inú ìsọ̀rí ìsọ̀rí, mo sì mẹ́nu ba díẹ̀ nínú wọn. Àkọ́kọ́ ni fídíò nípa **òṣèlú** (fún àpẹẹrẹ, ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ààrẹ àná, Olóyè Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́[9]) tó ní ṣe pẹ̀lú ètò ọ̀rọ̀ òṣèlú. Ìkejì ni fídíò nípa **èdè àti àṣà** àbí gbígbé èdè àti àṣà Yorùbá láruge (fún àpẹẹrẹ, ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Démiládé Elizabeth Líjọkà, ọmọ ọdún mẹ́sànán[10]). Ìkẹ́ta ni fídíò nípa **eré orí ìtàgé àbí orin kíkọ** (fún àpẹẹrẹ, ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Adéwálé Alébíoṣù[11]). Ìkẹ́rin ni fídíò nípa ọ̀rọ̀ **ẹ̀sìn** (fún àpẹẹrẹ, ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Sheik Taofeeq Akéwúgbagold lóri ìyàwó níní[12]). Èyí ṣe pàtàkì nítorípé púpọ̀ nínú àwọn Yorùbá gbàgbọ́ nínú ẹ̀sìn kan àbí ìmíràn. Ìkarùnún ni fídíò nípa **òwò** ṣíṣe àbí ìwúlò iṣẹ́ ṣíṣe (fún àpẹẹrẹ, iṣẹ́ ọkọ̀ fífọ̀ láti ọ̀rọ̀ Bùnmi Ọ̀pákúnlé[13]). Iṣẹ́ ṣíṣe ṣe pàtàkì fún àwọn ọmọ Yorùbá. Ìkẹfà ni fídíò nípa **iṣẹ́ àrà** tí àwọn èèyàn ń gbé

7 https://www.bbc.com/yoruba/56791124
8 https://www.bbc.com/yoruba/56235723
9 https://www.bbc.com/yoruba/afrika-47458579
10 https://www.bbc.com/yoruba/awon-iroyin-miran-63594183
11 https://www.bbc.com/yoruba/articles/ce51gx34v73o
12 https://www.bbc.com/yoruba/afrika-56797979
13 https://www.bbc.com/yoruba/51203005

ṣe ní àwùjọ wa (fún àpẹẹrẹ, iṣẹ́ ọpọlọ tí Ọlámidé Odùkọ̀yà[14] ń ṣe pẹ̀lú àwọn àlòkù irin láti ṣẹ̀dá àwọn oun tuntun). Ìkéje wà nípa **eré ìdárayá** (fún àpẹẹrẹ, ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Tóbilọ́ba Amúṣàán lẹ́yìn tó borí ní àgbáyé nínú ìdíje eré sísá oní ọgọ́rùnún mítà[15]) tí gómìnà ìpínlẹ̀ Ògùn fún ní ẹ̀bùn, tí ààrẹ Orílẹ̀-èdè Nàìjíríyà sì dá lọ́lá. Ìkẹ́jọ ni nípa **ìpèníjà ìlera** tí àwọn èèyàn má ń là kọjá (fún àpẹẹrẹ, ọ̀rọ̀ láti ọ̀dọ̀ Emeka Abugu[16]). Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí ṣe pàtàkì nítorípé bó ti lẹ̀ jẹ́ pé kìí ṣe èdè Yorùbá ni Emeka Abugu ń sọ, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa rí gbogbo nǹkan tí Emeka Abugu ń sọ kà lóri fídíò ní èdè Yorùbá. Nǹkan kan náà ni a má ń rí nípa ìròyìn láti **ilẹ̀ òkèrè** tó jẹ́ ìsọ̀rí ìkẹ́sànán tí mo ti máa dá ẹnu dúró, fún àpẹẹrẹ, ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Zahara láti Orílẹ̀-èdè South Africa[17] Mo ṣe ìtúpalẹ̀ ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ààrẹ àná, Olóyè Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́ ní ìsọ̀rí tó kàn ní ìsàlẹ̀.

## Ọ̀rọ̀ nínú fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Olóyè Ọbásanjọ́

Mo lo ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ààrẹ àná ti Orílẹ̀-èdè Nàìjíríyà, Olóyè Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́. Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí wáyé ní oṣù keji ọdún 2019. Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí ṣe pàtàkì nítorípé ní àkọ́kọ́, ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé gbogbo ọ̀rọ̀ nínú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà ni ó wà ní èdè Yorùbá. Ní ìkejì ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí ṣe pàtàkì nítorípé oríṣìí ọ̀rọ̀ ni ó jẹ yọ, fún àpẹẹrẹ, ọ̀rọ̀ nípa ẹ̀sìn, nípa ìlera, àti nípa òṣèlú. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé olóṣèlú ni ààrẹ àná Olóyè Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́, àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n sọ kìí ṣe nípa òṣèlú nìkan. Ẹ̀kọ́ ibẹ̀ ni pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà lè nílò láti sọ̀rọ̀ nípa àwọn nǹkan tí kìí ṣe nípa ẹ̀kọ́ tí wọ́n yàn láti kọ́ nìkan, fún àpẹẹrẹ, akẹ́kọ̀ọ́ tó fẹ́ di amòfin, lè mọ àwọn ọ̀rọ̀ kékèké nípa òwò ṣíṣe, nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ, nípa ìlera, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Mo kọ ọ̀rọ̀ fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú ààrẹ àná Orílẹ̀-èdè Nàìjíríyà, Olóyè Olúṣẹ́gun Ọbásanjọ́ kalẹ̀, ní ìsàlẹ̀.

> Nígbà tí à ń dàgbà, wọ́n ní ọmọ oko abẹ́dọlàǹlà, èmi ò mọ̀, bí ẹ̀dọ̀ àwọn ọmọ ilé, bó ṣe ń rí, ṣùgbọ́n àwa ò ní panadol nígbà tí à ń dàgbà. Aà ní Cerelac, àbí kíni wọ́n ń jẹ. Ọmú ìyá mi ni mo mu dàgbà, ni mo fi ń mùkọ. Bóyá wọ́n lágbo, àti àgúnmu, àgbo tí wọ́n fi ń wẹ̀ wá, àgúnmu tí wọ́n fi ń wẹ̀ wá, mi ò mọ̀. Ṣùgbọ́n mo rò pé oun tó ń ṣẹlẹ̀ sí mi ni ore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run Olódùnmarè, mo rò pé ore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run Olódùnmarè. Mo má ń sọ nígbà gbogbo pé Ọlọ́run dáa, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run Olódùnmarè, pé ó dá mi, ó sì fi ore ọ̀fẹ́ ẹ̀, ó fi jìínkí mi ju bó ṣe yẹ lọ. Ọlọ́run ó kọjú ṣe mí lóore. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ ẹ̀, torí gbogbo nǹkan ribiribi, nǹkan rere tí ó ti ṣẹlẹ̀ sí mi. Kìí ṣe mímọ̀ ṣe mi. Kìí ṣe ọgbọ́n inú mi. Kìí ṣe pé mo mọ̀ọ́ bẹ́, mo mọ̀ọ́ bò.

14 https://www.bbc.com/yoruba/afrika-49575710
15 https://www.bbc.com/yoruba/articles/cy9vy553e7jo
16 https://www.bbc.com/yoruba/afrika-51074434
17 https://www.bbc.com/yoruba/55119666

Ọlọ́run yọ̀nda ẹ̀ fún mi ni. Nígbà tí mo wà lẹ́wọ̀n, àwọn tí Abacha ń bá sọ̀rọ̀, ó ní àwa mẹ́ta ni aà ní jáde lẹ́wọ̀n àti tìmọ́lé lójú òun. Shehu Yar'Adua, igbákejì mi, ẹ mọ̀ bó ṣe jẹ́ sími. MKO Abíọ́lá, ilé-ìwé kan náà ni a jọ lọ, ọ̀rẹ́ mi ni; àti èmi. Àwọn méjì yókù ò jáde, mi ò fi yọ̀ wọ́n. Pé mo jáde, ore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run ni. **So** tí Ọlọ́run bá ṣe irú ore bẹ́ẹ̀ fún mi, kín ló dẹ̀ yẹ kí n ṣe padà fún Ọlọ́run ju pé kí n máa yìnín lọ. Kí n wá fi gbogbo ìgbésí ayé mi, pé màá fi sin Ọlọ́run, màá fi sin èèyàn. Gbogbo oun tó kù ní ìgbésí ayé mi, màá fi sin Ọlọ́run, màá fi sin èèyàn. Oun tó kù mí kù nì yẹn. Kíni mò ń wá tí Ọlọ́run ò ti ṣe fún mi? Kò sí. Kí Ọlọ́run wá fún mi ní ẹ̀mí gígùn àti àlàáfíà, kí gbogbo ore tí Ọlọ́run fẹ́ ṣe fún Nàìjíríyà láti jẹ́ kí Nàìjíríyà ó jẹ́ kan nínú àwọn ìlú tó máa lógo láyé, kó ṣ'ojú ẹ̀mí mi.

## Àlàyé ọ̀rọ̀ nínú fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Olóyè Ọbásanjọ́

Mo lo fídíò yìí pẹ̀lú àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mi ọlọ́dún ìkejì. Yàtọ̀ sí pé wọ́n ṣe kílàsì ọdún ìkíní, gbogbo wọn ni wọ́n ń sọ Yorùbá ní ilé. Mo la ọ̀nà tí mo fi kọ́ wọn kalẹ̀: (i) Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wo fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí ní ìgbà méjì, lẹ́yìn náà, (ii) olùkọ́ ní pé kí wọ́n kọ àwọn ọ̀rọ̀ tuntun tí wọ́n gbọ́ sílẹ̀, (iii) lẹ́yìn náà, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ tuntun àbí ọ̀rọ̀ tó ta kókó, olùkọ́ ṣe àlàyé wọn, (iv) lẹ́yìn náà, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì tó bá wọ́pọ̀ nínú fídíò náà (fún àpẹẹrẹ, 'So' tó wà nínú ọ̀rọ̀ ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà). Dípò lílo 'so', àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa wá ọ̀rọ̀ Yorùbá tó lè rọ́pò 'so', bíi '(ní)torí náà'. Ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì kò pọ̀ nínú àyọkà ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú Olóyè Ọbásanjọ́. Èyí ṣe pàtàkì láti jẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ ri pé ó ṣeéṣe láti sọ̀rọ̀ fún ìṣẹ́jú kan àbí méjì ní èdè Yorùbá láì lo ọ̀rọ̀ Gẹ̀ẹ́sì púpọ̀ àbí rárá. Èyí yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ àyálò tó ti di ti Yorùbá, fún àpẹẹrẹ, 'ọgọ́rùnún mítà'. Ìdí tó ṣe ṣe pàtàkì kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tọ́ka sí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni láti sọ ìtúmọ̀ wọn ní èdè Yorùbá, fún àpẹẹrẹ, àwọn ọ̀rọ̀ tí àwọn èèyàn púpọ̀ má ń sọ ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríyà bíi 'Mo like ẹ̀' dípò 'Mo fẹ́ràn ẹ̀' (ẹ wo Alabi, 2017). Lẹ́yìn èyí, (v) àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa gbọ́ fídíò náà ní ìgbà ẹ̀ẹkan si. Ní ìsọ̀rí ìsọ̀rí, (vi) wọ́n máa wá sọ àwọn kókó ọ̀rọ̀ nípa oun tí wọ́n ti gbọ́ nínú fídíò náà.

Àǹfàní iṣẹ́ yìí ni pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa kọ́ nípa ọ̀rọ̀ tuntun tí wọ́n ma máa lò, bíi 'jíìnkí mi'. Ìkejì ni pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa mọ̀ nípa àwọn ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ òṣèlú, ẹ̀sìn, ìlera, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí a kìí sábà kọ́ ní kílàsì. Ìkẹ́ta ni pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa ní ìmọ̀ nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ilẹ̀ Yorùbá, tí wọ́n lè má mọ̀ nítorí Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà ni wọ́n wà, fún àpẹẹrẹ, kí a mu àgbo fún ìlera pípé. Ìkẹ́rin ni pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa kọ́ nípa àṣà Yorùbá, fún àpẹẹrẹ, kí èèyàn máa dúpẹ́ lọ́wọ́ ẹni tó ju ni lọ, bí olóyè ṣe dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run.

Àwọn gbólóhùn ọ̀rọ̀ ìfarawé/ìjọra nípa ìlera jẹ́ **ewé**, **egbò**, **àgbo**, àti **àgúnmu**. Àwọn ọ̀rọ̀ yìí ṣe pàtàkì nítorípé ó ṣeéṣe pé akẹ́kọ̀ọ́ lè má mọ ìtúmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ yìí tó ní ṣe pẹ̀lú ìlera àti ìwòsàn. Ní àfikún, àwọn ọ̀rọ̀ bíi **panadol**

àti **cerelac** jẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ tí a lè fún ní orúkọ ní èdè Yorùbá. Àkọ́kọ́ ni ‘oògùn orí fífọ́’ àbí ‘oògùn ara ríro,’ àti ‘oúnjẹ ọmọ ọwọ́’. Bákan náà, àwọn ọ̀rọ̀ nípa ọ̀ṣẹ̀lú wà nínú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà, bíi **igbákejì**. Ní àfikún, àwọn orúkọ bíi Abacha, Yar’Adua àti MKO tọ́ka sí àwọn èèyàn nínú ìtàn Orílẹ̀-èdè Nàìjíríyà. Èyí lè jẹ́ oun pàtàkì fún akẹ́kọ̀ọ́ tó bá nífẹ̀ẹ́ sí ìtàn Orílẹ̀-èdè Nàìjíríyà.

Àwọn ọ̀rọ̀ tó ní ìtúmọ̀ tó jọra nì yìí: (i) **Kìí ṣe mímọ̀ ṣe mi**, (ii) **Kìí ṣe ọgbọ́n inú mi**, (iii) **Kìí ṣe pé mo mọ̀ọ́ bẹ́, mo mọ̀ọ́ bò**. Èyí ṣe pàtàkì kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ̀ pé oríṣìí ọ̀nà ni a lè fi sọ nǹkan. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ akẹ́kọ̀ọ́ ni wọ́n ti há ìkíni Yorùbá sí orí, fún àpẹẹrẹ, ‘Báwo ni, dáadáa ni, ilé ńkọ́, ó wà, iṣẹ́ ńkọ́, ó wà’ ṣùgbọ́n kìí ṣe irọ́ ni pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn èèyàn kìí kí ara bẹ́ẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá. Àwọn míràn ní ilẹ̀ Yorùbá, tí wọ́n bá kọ́kọ́ ríra ní ọjọ́ kan pàtó, á máa sọ pé ‘Ṣé àlááfíà ni’, àbí ‘Ẹǹlẹ́ o’, àbí ‘Ṣé o wà’, àbí ‘Ṣé gbogbo nǹkan ń lọ dáadáa’, àbí, ‘Ẹ pẹ̀lẹ́, ṣé iṣẹ́ ń lọ dáadáa’, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó ṣe pàtàkì kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kọ́ ju ọ̀nà kan láti lè sọ oun kan ní èdè Yorùbá. Ní àfikún, àwọn ọ̀rọ̀ bíi (iv) **nǹkan ribiribi** àti (v) **nǹkan rere** ní ìtúmọ̀ tó jọra. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ kófìrí pé wọn kìí lo ọ̀rọ̀ bíi ‘ribiribi’, nítorí náà, wọ́n fi ọ̀rọ̀ náà kún àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n ti mọ̀ tẹ́lẹ̀. Àwọn ọ̀rọ̀ míràn tó tún jọra ni (vi) **Ó sì fi ore ọ̀fẹ́ ẹ̀, ó fi jìnnkí mi ju bó ṣe yẹ lọ**, àti (vii) **Ọlọ́run ó kọjú ṣe mí lóore**. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mi kò gbọ́ ọ̀rọ̀ bíi **jìnnkí** rí. Nítorí náà, gbígbọ́ fídíò yìí ràn wọ́n lọ́wọ́ láti fi àwọn ọ̀rọ̀ tuntun yìí, kún àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n ti mọ̀ tẹ́lẹ̀.

## Ọ̀rọ̀ Ìparí

Iṣẹ́ yìí fihàn ìwúlò àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò lóri ‘BBC News Yorùbá’ àti bí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe lè ní àǹfàní láti sọ̀rọ̀ lóri ìṣẹ̀lẹ̀ oríṣìí ní ilẹ̀ Yorùbá látàrí ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò lóri ‘BBC News Yorùbá’. Mo ri pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́, tí mo bá ṣiṣẹ́, kọ́ àwọn ọ̀rọ̀ tuntun tí a ti tọ́ka sí, láti lè máa lo àwọn ọ̀rọ̀ náà pàápàá nínú ọ̀rọ̀ sísọ wọn. A lè ṣe àríyànjiyàn pé àwọn ọ̀rọ̀ kan wọ́pọ̀ láàárin àwọn àgbàlagbà ju àwọn ọmọdé lọ, ṣùgbọ́n èrò mi ni wí pé tí ọmọ kan bá dàgbà pẹ̀lú òbí rẹ̀, ọmọ náà lè kọ́ láti sọ ‘rárá’ fún ìdáhùn bẹ́ẹ̀kọ́ láti ọ̀dọ̀ àwọn òbí rẹ̀, ṣùgbọ́n tí àwọn òbí òbí ọmọ náà bá ń gbé nínú ilé náà, ọmọ náà lè kọ́ láti sọ ‘ó tì’ láti ọ̀dọ̀ òbí àwọn òbí rẹ̀. Bí ọmọ náà bá ń lo ‘rárá’ àti ‘ó tì’ nínú ọ̀rọ̀ sísọ, ó jẹ́ oun àǹfàní pàtàkì fún ọmọ náà àti fún ọjọ́ ọ̀la èdè Yorùbá ni. Òun ni Yorùbá Dialectal Model (YDM) tí mo gbé kalẹ̀ fi yé wa pé kò sí ìdí tó yẹ kí a máa lo ‘no’ (fún àpẹẹrẹ, nínú fíìmù Yorùbá tí a lè lò láti fi kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nínú kílàsì) nígbà tí a ní oríṣìí ọ̀nà láti sọ ọ̀rọ̀ náà ní Yorùbá bíi ‘rárá’, ‘ó tì’ àbí ‘bẹ́ẹ̀kọ́’. Fún iṣẹ́ àti ìwádìí ọjọ́ iwájú, a lè wo ìwúlò àwọn fídíò ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ti ní ọ̀pọ̀ èèyàn tí wọ́n ń sọ̀rọ̀ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ kan àbí ìmíràn àti àwọn ẹ̀kọ́ tí a lè kọ́ níbẹ̀. Èrò mi ni pé àwọn nǹkan tó bá kan ìlú, ìpínlẹ̀, àbí Orílẹ̀-èdè kan, tó sì kan àwọn èèyàn nínú ibẹ̀ ni a má ń rí èèyàn kan àbí méjì tí wọ́n máa ṣe ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú. Fún àpẹẹrẹ, ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú àwọn

bàbá àti màmá nípa ìṣẹ̀lẹ̀ àgbàrá omi tó ń jin kòtò sí ìlú wọn tó sì ń fa oríṣìí àjálù[18] àbí ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú àwọn tọkọtaya tí wọ́n bí ìbẹ́rin.[19] Olùkọ́ lè fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ọlọ́dún ìkejì àbí ìkẹ́ta ní iṣẹ́ láti kọ gbólóhùn ọ̀rọ̀ kan nípa ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò láti ìhà oníkálùkù tó sọ̀rọ̀ nínú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà. Iṣẹ́ ìwádìí yìí tún fi hàn pé ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò pẹ̀lú èèyàn kan á máa jẹ́ kí a mọ ọ̀pọ̀ nǹkan nípa ìhà tí ẹni náà kọ sí nǹkan. Ní ìparí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lè gba ìròyìn lóri 'BBC News Yorùbá' lóri òpó Facebook, X (Twitter), Instagram, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nítorí náà, ó máa dára púpọ̀ kí a máa lo àwọn ìròyìn pàápàá ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwo lóri 'BBC News Yorùbá' ní kílàsì wa nítorípé 'BBC News Yorùbá' jẹ́ oun èlò ojúlówó láti lò fún kíkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá ní Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà.

## Àwọn ìwé ìtọ́kasí


Akangbe, Clement Adeniyi (2020). The Form and Content of Ọbasa's Weekly Newspaper: The Yorùbá News. *Yoruba Studies Review*, 5 (1), 213-239.

Akinseloyin, Adefemi (2020). A Comparative Study of The Yorùbá News and Aláròyé Newspapers. *Yoruba Studies Review*, 5 (1), 267-280.

Alabi, Victor Temitope (2017). **Èdè Yorùbá, Ọ̀rọ̀ Àyálò àti Ọ̀rọ̀ Àdàpọ̀, àti Akẹ́kọ̀ọ́ Kíkọ́ ní ìlú Amẹ́ríkà**. *Yoruba Studies Review*, 1 (2), 33-38.

Alabi, Victor Temitope (2022). *Discursive Constructions of Selected Yoruba Speech Acts: Apologies, Refusals, and Sympathies*. Unpublished Doctoral Dissertation. Department of Linguistics, Indiana University.

Bolarinwa, Abidemi (2020). The Yoruba News as a Political Tool and Avenue for Cultural Revival. *Yoruba Studies Review*, 5 (1), 241-256.

Ibikunle, Tolulope (2020). Serialization of Ọbasa's Poems in The Yorùbá News. *Yoruba Studies Review*, 5 (1), 197-211.

Olunlade, Taiwo (2020). A Critical Assessment of Select Editorial Opinions in The Yoruba News. *Yoruba Studies Review*, 5 (1), 257-265.

Ọ̀ṣunnúgà, Olútọ̀lá (2013). Investigating Ambiguity in Headlines of Contemporary Yorùbá Newspapers. *Linguistics and Literature Studies*, 1 (2), 61-65.

Salawu, Abiodun (2004a). The Yoruba and Their Language Newspapers: Origin, Nature, Problems and Prospects. *Studies of Tribes and Tribals*, 2 (2), 97-104.

Salawu, Abiodun (2004b). Social Status as a Factor For The Readership of Yoruba Newspapers in Nigeria. *Nordic Journal of African Studies*, 13 (2), 200-215.

Salawu, Abiodun (2004c). A Readership Survey of Yoruba Newspapers for Development Messages. *Journal of Social Sciences*, 8 (3), 197-202.


18 https://www.bbc.com/yoruba/56658673

19 https://www.bbc.com/yoruba/afrika-66458917

Schleicher, Antonia (1997). *Yoruba Newspaper Reader.* Kensington, MD: Dunwoody Press.